# Ìlànà Ìbánisọ̀rọ̀ Ìgbàlódé àti Àṣà Yorùbá: Fífi Ọgbọ́n lo Idà Olójú Méjì

**Ayọ̀bámi Ọ̀jẹ́bọ̀dé, *Ph.D.***
*Department of Communication and Language Arts*
*Faculty of Arts, University of Ibadan*
*Ayo.ojebode@gmail.com*

**A Keynote Address presented at the 2016 Annual National Conference of Yorùbá Studies Association of Nigeria on 11th October, 2016 at Afẹ́ Babalọlá Hall, University of Lagos, Nigeria**

"Ẹni bá fi *Google* kọ́ Yòòbá; Olúwa rẹ̀ fẹ́ ṣìsọ ni" - Akéwì

## Ìfáárà

Fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdí, ọ̀rọ̀ ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé (modern ICT) ti di ohun tí àwùjọ gbọ́dọ̀ mójútó. Ìdí àkọ́kọ́ ni pé iye àwọn tó n lo àwọn ẹ̀rọ àti ìlànà wọ̀nyí pọ̀ gan-an ni. Ènìyàn mílíọ̀nù mẹ́rìndínlógún (16 million) ló ń lo *Facebook* ní Nàìjíríà; nígbà tí ènìyàn mílíọ̀nù ọgọ́jọ-ó-dín-mẹ́fà (154 million) ń lo ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ alégbèéká (NCC, 2017). Ní ọdún 2012, orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ló ṣe ipò kẹta láàrin àwọn orílẹ̀-èdè adúláwọ̀ nípa ìmúlò Túwítà (Twitter).

Ìdí kejì ni pé kìí ṣe pé àwọn tó ń lò ẹ̀rọ ìgbàlódé yìí pọ̀ nìkan, gbogbo ìgbà ni wọ́n tún ń lé sí i. Bí àpẹẹrẹ, àwọn tó ń lo

ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ní Nàìjíríà lọ́dún 2000 kò tó ìdá kan nínú ọgọ́rùn-ún. Ṣùgbọ́n láàrin ọdún mẹ́fà, wọ́n ti di ìdá mẹ́rìndínlọ́gọ́rin nínú ọgọ́rùn-ún (76%) (NCC, 2017).

Ìdí kẹta ni pé àwọn ẹ̀rọ àti ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ yìí ní ipa tí wọn ń kó nínú ìhùwàsí àwọn ènìyàn láwùjọ. Ìwádìí ìjìnlẹ̀ fi ye wa pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó ṣòro láti ṣe òṣùnwọ̀n gééré́gé lórí ipa rere tàbí àkóbá tí àwọn ẹ̀rọ àti ìlànà wọ̀nyí ń ṣe láwùjọ, ìdánilójú wà pé wọn kò salâì kópa rárá (Griffin, 2003).

Nínú àpilẹ̀kọ yìí, mo pe àkíyèsí sí àwọn àbùdá ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé èyí tó sọ wọ́n di nǹkan tí kò ṣe fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn. Lẹ́yìn náà ni mo wá ṣàlàyé oríṣiríṣi ọ̀nà tí àwọn ìlànà yìí fi ń ṣe àkóbá fún àṣà Yorùbá. Èyí tí ó dunni nínú jù nípa ọ̀rọ̀ yìí ni pé ọ̀pọ̀ ènìyàn ló ń ṣàmúlò àwọn ìlànà yìí láti mú ìdàgbàsókè bá àṣà Yorùbá. Nítorí náà, mo ṣe àlàyé díẹ̀ lórí àwọn irú ìṣàmúlò báyìí. Ní ìparí, mo fi ọ̀rọ̀ kọ́ sí ibi pé idà olójú méjì ni ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé jẹ́.

## Àbùdá Ẹ̀rọ àti Ìlànà Ìbánisọ̀rọ̀ Ìgbàlódé

Àwọn ohun tí à ń pè ní ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ni àwọn oríṣiríṣi ètò ajẹmọ́tàkùn àgbáyé (*world wide web*) bíi fífi àtẹ̀jíṣẹ́ ránṣẹ́ lórí íímeèlì (*email*) àti àwọn gbogbo ìlò ayélujára (*internet*), ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ alágbèéká àti àwọn ọ̀nà ìgbàròyìn ọlọ́pọ̀-èrò míràn.

Àìmọye ọ̀nà là ń gbà lo àwọn ìlànà wọ̀nyí. Kódà, ó ṣòro láti má ṣe àmúlò àwọn nǹkan yìí lójúmọ́.

Àwọn ètò àti ìlànà wọ̀nyí yàtọ̀ sí àwọn ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ayé àtijọ́ rí nípa àbùdá wọn. Ní àkọ́kọ́, wọn kò ní alámòòjútó tàbí alákòóso. Àwọn ìwé ìròyìn àtijọ́, ilé iṣẹ́ rédíò àti móhùnmáwòrán ní alámòòjútó. Kí ìròyìn tó jáde nínú ìwé ìròyìn tàbí gun orí afẹ́fẹ́, àwọn olótùú (*editors*) gbọ́dọ̀ wò ó fínnífínní láti rí i pé kò ṣẹ̀ sí òfin, kò sì tako àgbékalẹ̀ àwùjọ. Èyí kò rí bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀rọ àti ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé. Ẹnikẹ́ni ló le gbé ohunkóhun jáde ní orí ìtàkùn àgbáyé yálà ìròyìn, ìkéde, àwòrán, fọ́nrán fíìmù, abbl.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn nǹkan wọ̀nyí ló lòdì sí ìhùwàsí àti òfin àwùjọ. Àwọn tó dá *Facebook, Twitter* àti *Youtube* sílẹ̀ ń gbìyànjú láti ṣe òfin tí yóò dín àṣìlò wọ̀nyí kù. Bí àpẹẹrẹ, lẹ́yìn ìwọ́de àti ìjàngbọ̀n tó ṣẹlẹ̀ ní Charlottesville ní United States of America ní 2017, Olùdásílẹ̀ *Facebook*, Ọ̀gbẹ́ni Mark Zukerberg ṣe ìkéde pé *Facebook* ti ń yọ àwọn ìkéde àti ọ̀rọ̀ tó lòdì sí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn àwọn tí kìí ṣe aláwọ̀ funfun kúrò lórí *Facebook* (Wagner, 2017). Èyí nìkan kọ́, ọ̀pọ̀ ìjọba ló ń gbèrò láti fi òfin de àwọn àṣìlò wọ̀nyí ṣùgbọ́n wọn kò tíì ṣe àṣeyọrí.

Àbùdá kejì tí àwọn ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ní ni pé, wọ́n fún gbogbo ènìyàn ní ẹ̀tọ́ àti sọ̀rọ̀. Nípa èyí, wọn yàtọ̀ sí ìwé ìròyìn, rédíò tàbí móhùnmáwòrán tí ó fi àyè gbà àwọn òsìṣẹ́

oníròyìn nìkan láti sọ̀rọ̀ kí gbogbo ará ìlú sì wà ní ipò olùgbọ́ nìkan. Ní òde ìwòyí, gbogbo wa ni olùsọ àti olùgbọ́.

Ní àfikún, àwọn ẹ̀rọ àti ìlànà yìí tún kó oríṣiríṣi ọ̀nà ìsọ̀rọ̀ wọ ìlú: fídíò, àtẹ̀ránṣẹ́, ìyàwòrán-ránṣẹ́, ìfohùn-ránṣẹ́, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni wọ́n kó dé.

## Àkóbá tí Ìlànà Ìbánisọ̀rọ̀ Ìgbàlódé ń ṣe fún Àṣà Yorùbá

Àṣà ìbọ̀wọ̀fágbà ṣe pàtàkì láàrin àwọn Yorùbá. Kódà, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé gbogbo àìṣedéédéé tó ń ṣẹlẹ̀ láyé ń ṣẹlẹ̀ nítorí àìbẹ̀rù àgbà ni. Nínú ọ̀rọ̀ sísọ, àìsọ̀rọ̀, ìkíni àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, àwọn Yorùbá a máa fi ìbọ̀wọ̀ hàn fún àwọn àgbà. Tí Yorùbá bá sọ pé ọmọdé gbọ́n tàbí ó ní ẹ̀kọ́ ilé, nǹkan pàtàkì tí irú ọmọ bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ ní ni ìbọ̀wọ̀ fún àwọn àgbà. Ọmọ bẹ́ẹ̀ kò gbọdọ̀ pe àgbàlagbà lórúkọ, kò gbọdọ̀ fojú pa àgbàlagbà rẹ́, kò sì gbọdọ̀ máa ṣe ohun mìíran nígbà tí àgbàlagbà bá ń bá a sọ̀rọ̀.

Àwọn ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ti ń tako ọ̀pọ̀ lára àwọn àṣà àti ìṣe wọ̀nyí. Àpẹẹrẹ kan ni àtẹ tó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

**Àtẹ 1**




Èèwọ̀ ni nínú àṣà Yorùbá fún akẹ́kọ̀ọ́ láti pe olùkọ́ rẹ̀ lórúkọ. "Ayọ̀bámi" tí a rí nínú àtẹ yìí, olùkọ́ ni fún Tolú Mákindé; Tolú kò gbọdọ̀ pè é lórúkọ ṣùgbọ́n pẹ̀lú ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé, ó ṣòro fún Tolú láti pa òfin Yorùbá yìí mọ́.

Ibi tí ọ̀rọ̀ náà tún ti fara hàn púpọ̀ ni nínú ìtàkurọ̀sọ tó máa tẹ̀lé àwọn ìròyìn lórí ìtàkùn ayélujára. Lẹ́yìn tí àwọn èniyàn bá ka ìròyìn tán, wọn a tún máa fèsì sí ìròyìn náà; ọ̀rọ̀ ìkórìíra (hate speech), èébú àti èpè tí àṣà Yorùbá kò fàyè gbà ló máa ń jáde níbẹ̀. Nínú àwọn ìtàkurọ̀sọ tó tẹ̀lé ìròyìn wọ̀nyí, àwọn èèyàn a máa fi orúkọ burúkú pe ẹ̀yà ẹnìkejì – *Yorufools, Foolani, Biafraud.* Wọn a máa wọ́ òbí ẹnìkejì nílẹ̀. Àwọn nǹkan

mìíràn tí kò ṣe fetí gbọ́ ló pọ̀ nínú nǹkan tí wọn máa ń sọ. Àṣà Yorùbá lòdì sí irú ìwà àti ọ̀rọ̀ báyìí.

Èyí tó burú jù ni pé àwọn tó ń sọ ọ̀rọ̀ ìbàjẹ́ wọ̀nyí kò tilẹ̀ mọ̀ bóyá ọmọdé tàbí àgbàlagbà ni wọ́n ń bá sọ̀rọ̀. Nípa mímú ìfojúkojú kúrò nínú ọ̀rọ̀ sísọ, ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ti di ọ̀rọ̀ "òru kò mẹni ọ̀wọ̀" (Minerd, 1999).

Ní àfikún, ìwà àfojúdi ni kí wọn máa bá ènìyàn sọ̀rọ̀ kí onítọ̀hún máa ṣe nǹkan mìíràn lọ; tàbí kí ènìyàn wà láàrin àwọn ènìyàn láì kọbiara sí wọn. Ẹ jẹ́ kí á fi **Àtẹ 2** yìí gbe ọ̀rọ̀ wa lẹ́sẹ̀.




Fífi ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ alágbèéká sí ẹ̀gbẹ́ kan kí á sì kọbiara sí ẹni tí à ń bá sọ̀rọ̀, ìwà ọ̀wọ̀ ni. Ìwà àfojúdi tàbí ìfojú tẹ́ńbẹ́lú lòdì sí àṣà Yorùbá púpọ̀.

Ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé tún tako àṣà Yorùbá nípa àyè tí ó fi gba ìfihàn tàbí ìgbésóde àwọn ohun ọ̀wọ̀ (Ọ̀jẹ́bọ̀dé, Togundé àti Adélakùn, 2011). Àwọn ẹ̀yà ara ènìyàn tí kò yẹ kí á fi hàn;

àwòrán àti fídíò ìbálòpọ̀ ọkùnrin àti obìnrin, ọkùnrin àti ọkùnrin, obìnrin àti obìnrin, ènìyàn àti ẹranko; gbogbo ìwọ̀nyí ló ti wà ní àrọ́wọ́tó gbogbo ẹni tí ó ń lo ìtàkùn ayélujára lóde òní. Àwòrán ìranù wọ̀nyí (*pornography*) jẹ́ nǹkan tí àṣà Yorùbá kò fi àyè gbà rárá.

**Ìṣàmúlò Ìlànà Ìbánisọ̀rọ̀ Ìgbàlódé fún Ìgbélárugẹ Àṣà Yorùbá**

Bí àwọn ọ̀nà tí ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ṣe ń mú ìfàsẹ́yìn bá àṣà Yorùbá ṣe pọ̀, bẹ́ẹ̀ náà ni akitiyan àwọn ènìyàn láti fi àwọn ìlànà yìí gbé àṣà Yorùbá ga kò kéré. Ọ̀nà mẹ́ta ni àwọn ènìyàn wọ̀nyí ń gbà ṣàmúlò ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé láti gbé àṣà Yorùbá ga: ìtọ́jú (preservation), àtúnhun (re-formatting), àti ìṣẹ̀dá apilikéṣàn. Ọ̀nà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí ló sì so pọ̀ mọ́ ara wọn.

Ìtọ́jú àwọn èdè, orin, ijó, òwe, ọ̀rọ̀, ìlànà, ìṣe, ayẹyẹ ọdún àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ṣe pàtàkì fún àwọn tí kò fẹ́ sọ àṣà wọn nù (Van de meer, Smith and Pang, 2016). Ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé fi àyè sílẹ̀ láti ṣe ìtọ́jú àṣà Yorùbá; ọ̀pọ̀lọpọ̀ èèyàn, pàápàá jùlọ àwọn òṣèré àti àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ, ló sì ń ṣàmúlò àwọn ìlànà yìí láti rí i pé àṣà Yorùbá kò sọnù. Àpẹẹrẹ kan ni ti Túndé Kèlání TV. Ọ̀gbẹ́ni Túndé Kèlání, Olùdásílẹ̀ Òpómúléró (Mainframe Productions) gbajúmọ̀ fún lílo eré oníṣe fún ìgbélárugẹ àṣà. Nínú éré *Arugbá*, bí àpẹẹrẹ, oríṣiríṣi àṣà Yorùbá ni ó jẹyọ: ayẹyẹ

ọdún Ọ̀ṣun Òṣogbo, ètò ìṣèlú, àṣà ijó èwe ìgbàlódé, ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa oríṣiríṣi nǹkan bíi pípa ara ẹni mọ́ (*chastity*) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ eré Òpómúléró ló máa ń ní àwọn nǹkan wọ̀nyí nínú. Ní 2008, ilé iṣẹ́ náà bẹ̀rẹ̀ sí ní fi àwọn eré wọ̀nyí sí orí ìtàkùn àgbáyé ní ọ̀fẹ́. Wọ́n tún ń ṣe àfihàn eré àwọn òṣèré mìíràn pẹ̀lú. Ní orí *Youtube* (www.youtube.com/user/tkelani/featured) Alàgbà Túndé Kèlání ní ẹ̀ẹ̀dẹ́-gbà-a-à-sán-dín-mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n olùtẹ̀lé (16,875 subscribers); àwọn tí ó sì ti ya ibẹ̀ wo eré lé ní mílíọ̀nù mẹ́ta ó dín díẹ̀ (2.8 million).

Lórí fesibúùkù, a tún rí àwọn mìíràn bíi Yorùbá *Wedding*; Ẹwà Èdè Yorùbá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹnì kan tó ń jẹ́ Ẹ̀gbá Aláké ti ṣe àkójọpọ̀ orin àtijọ́ Yorùbá lọ́pọ̀lọpọ̀ sí orí Yúútuùbù. Orin S. Àká, Lìgálí Mùkáíbà, Ojindo, Kàmọ́rù Bọ́ḿbàtà, Yusuf Ọlátúnjí, Hárúnà Ìṣọ̀lá, Àyìnlá Ọmọwúrà, Bọ̀lọ̀jọ̀ Vasco da Gama, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ló wà níbẹ̀. Ní ọdún 2009 ni Ẹ̀gbá Aláké ṣí pẹpẹ *Youtube* tiwọn (www.youtube.com/user/EgbaAlake/featured). Ní ọdún 2017 yìí, ènìyàn tó lé dín díẹ̀ ní mílíọ̀nù mọ́kànlá (10.9 million) ló ti ya ibẹ̀ wòran; wọ́n sì ní ẹgbàá-mẹ́jọ olùtẹ̀lẹ́ (16,000 subscribers). Láì sí irú àwọn ọmọ Yorùbá bíi Ẹ̀gbá Aláké, Túndé Kèlání; láìsì sí ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé, à bá ti sọ púpọ̀ nínú àwọn àṣà àti ìṣe wọ̀nyí nù.

Ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ló ń ṣe àtúnhun (re-formatting) àwọn àṣà Yorùbá pẹ̀lú ẹ̀rọ àti ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé. Ọ̀pọ̀ àṣà Yorùbá ló wà ní kíkọ sílẹ̀, ọ̀pọ̀ sì jẹ́ àtẹnudẹ́nu. Àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ wọ̀nyí ń mú àwọn àṣà yí kúrò ní ipò tí wọn wà tẹ́lẹ̀ tí wọn sì ń fi wọ́n sí àbùdá ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé. Àpẹẹrẹ ni ọ̀pọ̀ iṣẹ́ African Languages Technology Initiative (ALT-I). ALT-I ti sọ ọ̀pọ̀ ìwé lítíréṣọ̀ Yorùbá àtijọ́ di ìwé tó ń sọ̀rọ̀ (audio books) kí àwọn tí kò le kàwé ba lè gbádùn wọn. Àwọn ìwé Olóògbé Fágúnwà wà lára àwọn ìwé náà. Pẹ̀lú iṣẹ́ àtúnhun wọ̀nyí, àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ yìí ń mú kí àṣà Yorùbá tún di mímọ̀ síwájú síi. Àwọn kan ti ṣe àtúnhun ọpọ́n Ifá àti odù Ifá.

**Àtẹ 3**




Wọ́n ti sọ ifá di apilikéṣàn (app).

Ó ti ṣeéṣe báyìí láti bá Ifá sọ̀rọ̀ láìsí Babaláwo níbẹ̀. Tí ènìyàn bá ti ra apilikéṣàn yìí tí ó sì ká a sínú ẹ̀rọ àgbéká (mobile device), kí onítọ̀hún máa bá Ifá sọ̀rọ̀ lọ ni.

Yàtọ̀ sí síṣe àtúnhun àti ìṣẹ̀dá apilikéṣàn (applications), oríṣiríṣi ni àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ ń ṣe. ALT-I ṣẹ̀dá apilikéṣàn tó ń fi èdè Yorùbá rán àwọn aláìsàn létí láti lo òògùn wọn. Ó tún sẹ̀dá òmíràn tó ń túmọ̀ òwe ìlù dùndún sí ọ̀rọ̀. Ọ̀gbẹ́ni Kọ́lá Ọlátúbọ̀sún ṣẹ̀dá apilikéṣàn tó ń sọ ìtumọ̀ orúkọ Yorùbá.

**Àtẹ 4**




Ṣíwájú gbogbo èyí, ọdún 2002 ni Ọ̀mọ̀wé Túndé Adegbola, Olùdásílẹ̀ ALT-I, ti ṣe àtẹ ìtẹ̀wé tó ń tẹ èdè Yorùbá. Látàrí iṣẹ́ yìí, àjọ United Nations fún Ọ̀mọ̀wé Adégbọlá ní àmì

èyẹ ní 2003. Díẹ̀ ni àwọn yìí nínú àwọn tó ń fi ìṣẹ̀dá apilikéṣàn mú ìlọsíwájú bá àṣà Yorùbá.

Ara ìṣẹ̀dá apilikéṣàn ni àwọn iṣẹ́ *Google* tó ń túmọ̀ oríṣiríṣi èdè ní Yorùbá, tí ó sì ń túmọ̀ Yorùbá sí oríṣiríṣi èdè. Ọ̀mọ̀wé Túndé Adégbọlá ti African Languages Technology Initiative (ALT-I) yìí ti ṣe iṣẹ́ takuntakun lórí èyí. Ara iṣẹ́ wọn ló jẹ́ kí a ní *Microsoft Office* ní èdè Yorùbá, Hausa ati Igbo. Pẹ̀lú èyí, àǹfààní wà fún àwọn òǹlo èdè Yorùbá láti lo oríṣiríṣi irinṣẹ́ tó wà nínú *Microsoft Office*.

Àwọn ìgbiyànjú wọ̀nyí sì ń tẹ̀síwájú pẹ̀lú iṣẹ́ ìwadìí oríṣiríṣi. Ọ̀pọ̀ wọn kò tíì wẹ yán kàǹkàn. **Àtẹ 5** tó wà nísàlẹ̀ yìí fi hàn irú akùdé tó wà lára díẹ̀ nínú wọn.




Nínú ìtumọ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí a rí lójú *translate.google.com.ng* yìí, méjì kùnà pátápátá. Pàápàá jùlọ, "Akin mi ọwọn" jìnà púpọ̀ sí "I'm sorry" bẹ́ẹ̀ ni "ẹgbẹ́" kìí ṣe "partner". Nínú ọ̀rọ̀ tí mo bá Ọ̀mọ̀wé Túndé Adégbọlá, sọ, wọ́n wòye pé iṣẹ́ ìfi ẹ̀rọ túmọ̀ èdè (*machine*

*translation*) kìí ṣe iṣẹ́ èdè tàbí iṣẹ́ ẹ̀rọ nìkan bí kò ṣe àjùmọ̀ṣe àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ àti onímọ̀ èdè.

**Ìkádìí: Fífi Ọgbọ́n lo Idà Olójú-méjì**

Pẹ̀lú àwọn àlàyé àti àpẹẹrẹ tí a ti ṣe yìí, ó hàn pé bíi idà olójú méjì ni ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé jẹ́. Bí ó ṣe ń ṣàkóbá fún àṣà Yorùbá, bẹ́ẹ̀ náà ni à ń lò ó láti gbé àṣà ga. Fún ìdí èyí, a ní láti fi ọgbọ́n lo idà yìí kí rere tí ó ń ṣe ba le pèlé síi, kí àkóbá rẹ̀ fún àṣà wa sì le dín kù.

Àjọṣe gbọ́dọ̀ wà láàrin àwọn onímọ̀-ẹ̀rọ kọ̀mpútà tó ń ṣẹ̀dá apilikéṣàn àti àwọn onímọ̀ nípa èdè, ìṣe àti àṣà Yorùbá. Àjọ àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ Yorùbá le ṣàkóso irú àjọṣepọ̀ yìí.

Àjọ tó ń polongo ìdàgbàsókè Ìwọ̀-oòrùn Nàìjìríà (Development Agenda for Western Nigeria, DAWN) lè ṣe agbátẹrù ìdíje láàrin àwọn onímọ̀-ẹ̀rọ lórí oríṣiríṣi ọ̀nà láti fi ìtàkùn àgbáyé gbé àṣà Yorùbá lárugẹ. Bí obìnrin kò jowú, ọbẹ̀ rẹ̀ kìí dùn, láìsí ìdíje, ìlọsíwájú kò le yá kánkán.

Àwọn alámòójútó ètò ẹ̀kọ́ ní àwọn ìpínlẹ̀ tó wà ní Ìwọ̀-Oòrùn ní láti ṣe àtúnṣe sí ètò ẹ̀kọ́ Kọ̀mpútà ni àwọn ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti girama. Bí àwọn èwe bá ti ń kọ́ lílò àwọn ẹ̀rọ wọ̀nyí ni kí wọ́n sì máa kọ nípa àléébù tó wà níbẹ̀ àti bí a ṣe le lò wọ́n láti gbé àṣà Yorùbá ga.

Iṣẹ́ púpọ̀ wà lọ́wọ́ àwọn òbí. Lóòótọ́ ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé kò dà bíi tẹlifísàn tó ní ìjánu (remote control), èyí kò sọ pé òbí kò le kó ìlò àwọn ẹ̀rọ wọ̀nyí ní ìjánu. Àwọn tó ń sèdá apilikéṣàn ti ń ṣe ìjánu òbí (parental control) tí òbí le fi dènà àṣìlò àwọn ẹ̀rọ bíi fóònù alágbèéká àti *tablets* lọ́wọ̀ àwọn ọmọ wọn.

**Ìdúpẹ́**: Mo dúpẹ púpọ̀ lọ́wọ́ Alàgbà Túndé Kèlání, Ọ̀mọ̀wé Túndé Adegbọla àti Omidan Dindy van Maanen fún ìrànlọ́wọ́ wọn.

**Ìwé Ìtọ́kasí**

Griffin, E. A (2003). *A new look at communication theory.* Boston: McGraw Hill.

Minerd, J. (1999). "The Decline of Conversation: With everyone wired, we are starved of face-to-face conversation". *The Futurist* 33(2) Academic OneFile.

NCC, Nigerian Communications Commission (2017). "Industry Statistics" http://www.ncc.gov.ng/stakeholder/statistics-reports/industry-overview.

Ojebode, A.; Togunde, D. and Adelakun, A. (2011). Secrecy, Security and Social Exchange: New Media and Cross-Generational Dating in Nigeria. *International Journal of Sociology of the Family*. Vol. 37. No. 2, pp. 307-327.

Van Der Meer, Sarah and Smith, Stephen & Pang, Vincent. (2016). The Use of ICT to preserve Australian Indigenous Culture and Language - a Preliminary Proposal using the Activity

Theory Framework – A conference paper: https://www.researchgate.net/publication/303821713_The_Use_of_ICT_to_preserve_Australian_Indigenous_Culture_and_Language_-_a_Preliminary_Proposal_using_the_Activity_Theory_Framework.

Wagner, K. (2017). "Mark Zuckerberg says Facebook is taking down posts and 'watching the situation closely' in Charlottesville" Recode https://www.recode.net/2017/8/16/16158940/mark-zuckerberg-facebook-charlottesville-nazis.